# Wútùwútù Yáákí[1]

Ọlábíyi Babalọlá Yáì[2]
Department of Linguistics and African Languages
Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀
Ọ̀ṣun State, Nigeria.

Wútùwútù yáákí;
Wútùwútù yám̀bèlé;
Ká súré pátápirá,
Ká fẹ̀wù àlàárì fọnkun àmódi;[3]

Ẹsẹ Ifá yìí jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ifá ńláńlá tí a fà yọ kúrò nínú Òtúá Méjì. Méjì ni àwọn onímọ̀-èdè Yorùbá tó ti yẹ ẹsẹ Ifá wò fínífíní pẹ̀lú ìjìnlẹ̀ ìmọ̀ òde òní nípa èdè tí a ń pè ní lìǹgúísítíkì. Ẹni àkọ́kọ́, Ọ̀gbẹ́ni 'Wáǹdé Abímbọ́lá la ẹsẹ Ifá sí ọ̀nà mẹ́jọ.[4] Ọlátúndé Ọlátúnjí ni ẹnì kejì; òun pín ẹsẹ Ifá sí ìsọ̀rí méje.[5] Gẹ́gẹ́ bí a ó ṣe rí i ní ìsàlẹ̀ (ẹ wo àlàyé 2), àwọn àyẹ̀wò méjèèjì tí a dárúkọ wọ̀nyí pọwọ̀ léra. Nínú àdìtú wa yìí, ètò ẹsẹ Ifá onídàáméje ni a ó mùú lò nítorí pé ó dà bí ẹní bá ẹsẹ Ifá yìí mu jù lọ. Nínú ìdá èkìíní (Ìlà 1 dé 8), a lè pín àwọn gbólóhùn ibẹ̀ sí oríṣìí mẹ́ta.

1 Wọ́n kọ́kọ́ tẹ àpilẹ̀kọ yìí jáde nínú ìwé àtìgbàdégbà *Yorùbá* tíí ṣe jọ́nà Ẹgbẹ́ Onímọ̀ èdè Yorùbá ti Nigeria ni ọdún 1976.

2 Òǹkọ̀wé yìí ti di olóògbé báyìí.

3 Ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ẹsẹ Ifá náà wà ní Àfikún II ní ìparí àpilẹ̀kọ yìí.

4 "Nearly all *ẹsẹ Ifá* have a maximum of eight main parts: (i) name(s) of the Ifá priests involved in a past divination, (ii) name(s) of the client(s) for whom the divination was performed, (iii) reason for the divination, (iv) the instruction of the Ifá priest(s) to the client(s) after the divination (v) whether or not the client complied with the instructions, (vi) what happened to the client(s) after he carried out or refused to carry out the instructions, (vii) the reactions of the client(s) to the joy or sorrow that resulted from the process of divination, (viii) the moral from the story as a whole." Láti inú tísíìsì Wande Abimbọla, *An Exposition of Ifá Literary Corpus*, University of Lagos, 1969, ni a ti fa àwọn àyọlò yìí kúrò.

5 (i) citation, (ii) presentation of the client, (iii) Ifá's commands, (iv) reaction of the protagonist, (v) result of the protagonist's reaction, (vi) intra-structural recapitulation (optional), (vii) general comments. Láti inú tísíìsì Ọlátúndé Ọlátúnjí, *Characteristic Features of Yorùbá Oral Poetry*, University of Ibadan 1971, ni a ti fa àwọn àyọlò yìí kúrò.

Ìlà láti 2 fi ara jọ ara. Bí a bá sì là wọ́n wò, a ó rí i pé sítírọkíṣọ̀ kan náà ni wọ́n ní. Ìlà 3 àti 4 ní sítírọkíṣọ̀ oní-kí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀rọ̀ tí a sọ nínú ìlà méjì wọ̀nyí yé ni láìsí àníàní, a lè sọ síbẹ̀ pé wọ́n ṣe bí ẹni ṣàjèjì sí gírámà Yorùbá ní ọ̀nà méjì. Àkọ́kọ́, ipò tí *pátá-pirá* wà ní ìlà 3 yìí kì í ṣe ipò tí a sáábà máa ń rí i. Kí a fi *pátápirá* tẹ̀ lé fáàbù kò wọ́pọ̀. Bí ó bá ṣe ẹ̀yán ọ̀rọ̀ míràn gẹ́gẹ́ bí *tètè* ni a rí ní ipò yìí ni kì bá tí sí ìyànilẹ́nu.

Lọ́nà kejì ẹ̀wẹ̀, bí a bá fi gírámà Yorùbá wọn àpapọ̀ 1 ìlà 3 àti 4, a lè sọ pé gbólóhùn tí ó là wọ́n já kò pé, kò sì kún. Nítorí pé bí a bá fi *kí* bẹ̀rẹ̀ gbólóhùn kan, a gbọdọ̀ fi ìdàjìi gbólóhùn míràn gbè é lẹ́sẹ̀ ni, eléyìí ìbáà ṣe gbólóhùn oní-kí bákan náà tàbí irú gbólóhùn tàbí kílọ̀ọ̀sì oní sítírọkíṣọ̀ míràn. Fún àpẹrẹ:

1. kí a ké sí wọn ki a tóó lọ (Ìyẹn kò yẹ ọmọ lú àbí)
2. kí á lọ jalè ní ilé àna ẹni (ǹjẹ́ èyí ha dára bí)

## Nìjẹ́ a lè ka ìlà 3 àti 4 sí ìsẹ́kù gbólóhùn?

Gbólóhùn kan ṣoṣo náà ló la àwọn ìlà 5 dé 8 já. Gbólóhùn ọ̀hún sì ní kí nínú. Ṣùgbọ́n a kò lè ṣaláìṣàkíyèsí pé àtò-ódì ni a to àwọn àmúlù inú gbólóhùn yí. Dípò bí + NP[6], NP + bí ni a rí níbẹ̀.[7] NP èyí tíí ṣe orúkọ ni a kọ́kọ́ fi bẹ̀rẹ̀ gbólóhùn yí láti fi han pé ẹyọ ọ̀rọ̀ yí (lékèélékèè) jẹ́ kókó ọ̀rọ̀ nínú gbólóhùn náà àti nínú gbogbo ewì ọ̀hún pàápàá. Ǹjẹ́ kí a lè baà ya orúkọ (lékèélékèé) sí ọ̀tọ̀ ni babaláwo akéwì yí ṣe fi í sí ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn náà kí ó tó wáá fi gbólóhùn oní-bí parí rẹ̀.

Ilà 5 yóò dá wa padà sẹ́hìn díẹ̀ láti tún ìlà 1 àti 2 yẹ̀ wò. Sítírọkíṣọ̀ rẹ̀ ran ni lọ́wọ́ láti le fún àwọn ìlà 1 àti 2 ní ìtúmọ̀ pípé. Lóòótọ́, ọ̀rọ̀ dún-bí-mo-ti-dún (onomatopoea) ni wọ́n láìsí àníàní; ṣùgbọ́n a tún lè fún wọn ní ìtúmọ̀ míràn. A kò lè sọ wí pé èèyàn ń wá òfíntótó ọ̀rọ̀ tàbí pé a ń wá ohun tó ń bẹ lápòo ṣòkòtò lọ sí Sókótó tí a bá wútùwútú yáákí sí ẹ̀dà (transform):

A kò sí déédé la ọ̀rọ̀ yí báun. Ìdí abájọ ni pé, lákọ̀ọ́kọ́, nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹsẹ Ifá ni a ti ń rí gbólóhùn tí sítírọkíṣọ̀ wọ́n ní ọ̀rọ̀-dún-bí-mo-ti-dún bẹ́ẹ̀, tàbí idio-fóònù tí í ṣe ọmọ ìyá rẹ̀, tí wọn sì fi awo, ọmọ, ló díá fún… àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, so pọ̀ mọ́ ẹyọ ọ̀rọ̀ tó kù. Fún àpẹẹrẹ:

1. Ìtarúkú, awoo wọn lóde ìtarúkú;
   Ìtarùkù, awo Ìtarùkù;
   Rùkùrúkù-tataata (Ìrosùn Méjì Ẹsẹ 1)[8]

---

6 A kò lè ya gírámà Yorùbá sí ọ̀tọ̀ nítorí pé Lìǹgúísítíìkì ti kọ́ wa pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀rọ̀ bíi fáàbù, bí orúkọ abl., ló kó gbogbo èdè pọ̀. Èyí ló mú kí a máa fi orúkọ kan náà pè wọ́n kí á sì máa fi lẹ́tà kan náà tọ́ka sí wọn nígbà tí a kò bá fẹ́ pè wọ́n ní àpètán, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn lẹ́tà bí, Q, C tàbí V kò sí nínú àbídí Yorùbá.

7 Fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé, ẹ wo: Ayọ̀ Bámgbóṣé, *A Grammar of Yorùbá*, o.i. 62.

8 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá, Apa 1*, Ìrosùn Méjì, ẹsẹ èkíní, o.i. 62.

2. Keesekeese lẹ ti ńrí
   Kààsàkààsà ḿbọ̀ lẹ́yìn
   Kààsàkààsà baba a keesekeese. (Ọ̀bàrà Méjì).[9]

Lọ́nà kejì, wútùwútù àti lékèélèkèé kò ṣàì fi ara jọ ara nípa sítírọ́kíṣọ̀ wọn ní ọ̀nà fonọ́lọ́jì. Àwítúnwí ọ̀rọ̀ onísílébù méjì, tí wọn ní kọ́ńsónáǹtí méjì ṣùgbọ́n fáwẹ̀lì kan náà ni wọ́n ń ṣe: $C_1 VC_2 V$.

Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, *lékèélékèé ẹyẹ ìmọ̀lẹ̀* dà bí gboùngboùn *wútùwútù yáḿbèlé*: A lè ka ìmọ̀lẹ̀ àti yáḿbèlé sí alákùdé ráímù.

Kín wáá ni àṣẹyìnwá àṣẹ̀yìnbọ̀ sítírọ́kíṣọ̀ ìdá kìíní ẹsẹ Ifá yìí? Ó fi hàn ni pé babaláwo fẹ́ẹ̀ fi yé ni pé òún ṣẹṣẹ bẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí ni o, ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ kù lẹ́hìn tó pọ̀. Báun ni a lè túmọ̀ ààbọ̀ ọ̀rọ̀ tí ń bẹ lára sítírọkísọ̀ oní-kí. Àti pé sítírọ́kíṣọ̀ gbólóhùn àwọn ìlà 6-7 tilẹ̀ fi àwọ̀ jọ àlọ́ àpamọ̀ tí a ti fún ní ìtúmọ̀ tàbí ìdáhùn rẹ̀ kí a tóó pa á. Kódà gbólóhùn abájọ (protasis) tilẹ̀ ni ètò ọ̀rọ̀ tí a tò sínú àwọn ìlà wọ̀nyí. Ní ọ̀rọ̀ kan, a tẹ́ní Ifá ni, à kòì tíì kì í, bẹ́ẹ̀ ni ìjìnlẹ̀ ìtúmọ̀ ìdá kìíní ẹsẹ Ifá yìí. Ṣé ***"mò ń bọ̀ n èè ṣe tán"*** náà ni àwọn akéwì fi í bẹ̀rẹ̀ ipa titun nínú ewì wọn, ***"ó dọ̀ dẹ̀dẹ̀ nìbẹ̀rẹ̀"*** sì ni èdè Ifá alára.[10] Bí a bá fi ojú gírámà wò wọ́n, ṣe ló yẹ kí á kó ìdá 2 àti 3 pọ̀ fún àyẹ̀wò, nítorí pé ṣe ni babaláwo hun wọ́n pọ̀. Bẹ́ẹ̀ náà ló sì hun ìdá 3 àti 4 pọ̀ (ìlà 9-18). Ara ìdá kẹrin ni ìlà 12 í ṣe (ó sì rú u) Ìdá 3 tún bẹ̀rẹ̀ láti ìlà 13 dé 17. Èyí ni pé ìdá 3 kò fi bẹ́ẹ̀ lọ tààrà. Ní ìkì fèlèku-fèlèjí ni akápọ̀ náà kì í. Ó mòòkùn, ó tún sọ jáde bí ẹja omi ni. Ìdá 3 kọ́ kọ́ wọlẹ̀ lẹ́hìn ìlà 11 ó sì tún ṣẹ́ jáde láti ìlà 13 dé 18. Ìlà 11 dúró fún odindin ọ̀rọ̀; ìlà 13 dé 18 odindi ọ̀rọ̀ là yíí sí wẹ́wẹ́. Ìbátan tó wà láàrin odindi àti ẹ̀wẹ́, ni irú ìbátan tí ń bẹ làárín wọn.

Àwọn ìlà 13 dé 17 tẹ́ ẹní aláwìítúnwí sílẹ̀ salau. Bẹ́ẹ̀ ni a sì gbin ṣẹ́gímà (Zeugma) sí àárín wọn (bẹ̀rẹ̀ láti ìlà 15). Ségímà yìí ṣe pàtàkì fún ìṣíṣẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí. A kò ṣàdéédé fo gbólóhùn *"kí"* ru nínú àwọn ìlà 15, 16 àti 17. Ohun tí o mú babaláwo fo gbólóhùn yìí ru ni pé àwọn orúkọ tí a fi ṣe àfikún fáàbù ìṣe nínú ìlà 15 dé 17 gùn ju àwọn ojúgbà wọn ti ìlà 13 àti 14 lọ. Àwọn orúkọ ti ìlà 15 dé 17 ní sílébù mẹ́rin, mẹ́ta gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe tẹ̀lé ara wọn (obídìẹ, ewúrẹ́, ẹinlá) níbi tí ojúgbà wọn ní sílébù méjì péré (eku, ẹja). Èyí un ló jẹ́ kí sẹgímà tí à ń wí yìí lè wáyé. Àfikún fáàbù ìṣe kan ṣoṣo (rú) ni àwọn ìlà 14 dé 17 í ṣe. Sítírọ́kíṣọ̀ kan náà ni a ó sì rí nínú gbogbo àfikún wọ̀nyí, èyí ni: Orí-Ẹ̀yán (HQ). A sì tún lè tú Ẹ̀yán ọ̀hún sí Q…Num + Adj (Ọ̀rọ̀ iye àti ọ̀rọ̀ àpèjúwe). Mọfọ́lọ́jì ọ̀rọ̀ àpèjúwe yìí ta kókó. Títú rẹ̀ fi ẹyọ ọ̀rọ̀ méjì hàn ni: àfikún apá òsì (abi-, oni-) àti idiofóónù. Ìlà 17 nìkan ló yapa nítorí pé ẹ̀yán tirẹ̀ ní *tí* nínú. Ní àkótán, sítírọ́kíṣọ̀ ìdá 3 jọjú, ó sì pegedé. Ó wáá dà bí ẹni pé bí wọ́n ṣe ń tẹ̀ lé ara wọn un, ijóo rí-bí-mo-ti-rí, dà-bí-mo-ti-dà ló ṣá ń fa oníkálùkù ìlà wọ̀nyẹn

9 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá, Apá* 2, o.i. 110.
10 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá*, Apá 2, o.i. 57

lẹ́ṣẹ̀. Wọ́n bá ara wọn ṣe déédé, Ìdí nìyí tí àkọ́sórí wọn rọrùn láìsí ìsọ̀yè fún àti babaláwo àti ọ̀gbẹ̀rí.

Ohùn ìtàn ni a fi sí ìdà kaàrún (ìlà 20 dé 68). Gbólóhùn gírámà tó tọ́ka sí àkókò ni àmì ohùn ìtàn yí: *ìgbà tí.* Kí a lè baà mọ̀ bí ìtàn ṣe ṣe pàtàkì tó ní ìdá yìí; a ní láti ṣàkíyèsí pé ẹ̀ẹ̀mẹ́fà ni àmì yí *(ìgbà tí)* yọ jáde níbẹ̀. (A lè rí i nínú àwọn ìlà 21, 23, 28, 35, 53 àti 62). Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìdá yìí fi ara jọ ìtàn púpọ̀, tí a sì le tìtorí rẹ kà á sí ọ̀rọ̀ gbẹrẹfu, yàtọ̀ fún ohun ti a lè kà sí ewì, síbẹ̀síbẹ̀ kò ṣaláìní ẹwà tirẹ̀. Èyí hàn nínú sítírọ́kíṣọ̀ rẹ̀. Àwọn ìlà tó bá ara wọn ṣe dédé ni babaláwo wáá fi dárá bí ilẹ̀ bí ẹníníbí. Bẹ́ẹ̀ sá ni a le ka àwọn ìlà 19, 21, 23 àti àwọn tó tẹ̀ lé ọ́kọ̀ọ̀kan wọn (20, 22, 24) si. A tilẹ̀ rí i pé gbólóhùn kan ṣoṣo náà ló kó àwọn ìlà tí a dárúkọ wọ̀nyí já láti òkè dé ilẹ̀. Sítírọ́kíṣọ̀ àwọn ìlà tí a kọ́kọ́ dárúkọ ni: Àfikún nípa àsìkò-àpólà gbólóhùn olórúkọ-àpólà gbólóhùn onífáàbù, (Adjunct-NP-VP). Tí èkejì sì ni: àpólà gbólóhùn olórúkọ-Àpólà gbólóhùn onífáàbù-Àpólà gbólóhùn olórúkọ-Àpólà gbólóhùn onífáàbù-Àpólà gbólóhùn olórúkọ (NP – NP). Ìlà ìkẹ́hìn ti ọ̀wọ́ tí a mẹ́nu bà yí ya ara rẹ̀ sọ́tọ̀ (ìlà 24): NP kejì inú rẹ̀ gba ẹ̀yán (èyí tí ìṣe ọmọ…ìlà 25). Ìjìnlẹ̀ ìtúmọ̀ ẹ̀yán yìí ń bọ̀ lẹ́hìn.

Kókó ọ̀rọ̀-bí-ìtàn, tí a sọ wí pé ó ṣe pàtàkì nínú ìdá 5 yìí, láti ẹsẹ 36 dé 48 ló jọba sí. Ògédé *wọn* ni babaláwo fi ń pilẹ̀ gbogbo ìlà ibẹ̀. *"Wọn"* yìí dúró fún àwọn èèyàn tí wọ́n ní ìpín nínú ohun tí ẹsẹ Ifá tọ́ka sí. Fáàbù ìṣe ni a fi tẹ̀lé gbogbo àwọn *"wọn"* wọ̀nyí. Nígbà míràn fáàbù ìṣe yìí a ní àfikún, nígbà míràn ẹ̀wẹ̀ a le fẹ́ àfikún kù. Ìṣísẹ̀ ìdá yìí yàtọ̀ gidigidi.

Bẹ́ẹ̀ náà sì ni ìṣísẹ̀ yí ní ìjìnlẹ̀ ìtúmọ̀: A ó rí í pé àwọn ìlà tí fáàbu ìṣe wọn jẹ mọ́ iṣẹ́ tàbí ìṣe tó le gba ni lákòókò, gùn ju àwọn ìyókù lọ. Àwọn ìlà yìí nìkan ló sì ní fáàbù aláfikùn. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ kí a fi àwọn ìlà 36 dé 41 wé ìlà 43 dé 45 wò.

| | |
|---|---|
| Wọ agbádá náà | foríí kanlẹ̀ |
| Wé gèlè náà sórí bàǹtùtù bantutu | dìde |
| Na igi mẹ́rin sílẹ̀ níbùú níbùú | kúnlẹ̀ |
| Kó sí àárin igi náà | nàró |

Ṣùgbọ́n ṣe ni àwọn ìlà tó ní fáàbù tó jẹ mọ́ ìṣe tí kò gba àkókò púpọ̀ kúrú: ṣàṣà nínú wọn ló ní fáàbù tó gba àfikún; àti pé VP wọn tó tẹ̀ lé *"wọn"* kì í sábàá ní ju sílébù méjì lọ (forí kanlẹ̀, dìde, kúnlẹ̀, nàró).

Ìkadìí ètò sítírọ́kíṣọ̀ yìí ni pé ìṣísẹ̀ rẹ̀ kọ́kọ́ wúwo ní ìbẹ̀rẹ̀ ìtàn yí; ìtàn ọ̀hún kò gbésẹ̀ nílẹ̀ bọ̀rọ̀. Ṣùgbọ́n bí a ti ń sún mọ òpin, bẹ́ẹ̀ ni ìṣísẹ̀ tún fi ń yá sí i, nítorí pé àwọn gbólóhùn fúyẹ́ sí i. Ìṣísẹ̀ wáà di ganran ganran nígbà tí iná ìtàn wá ńjó lọ sórí kókó. Ní ìdá 5 yìí náà la rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìlá tí í mú ni dá ẹsẹ Ifá mọ̀ gẹ́gẹ́ bí:

Ikú kò pa wọ́n,
Àrùn kò ṣe wọ́n.

tàbí pàápàá jùlọ:

Ọ̀rúnmìlà kọ́ wọn ní dídá ọwọ́
Wọ́n mọ̀ ọ́n dá… àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ

Àwítúnwí alákùdé ni akéwì fi hun aṣọ ẹwà ẹsẹ Ifá yìí níbí. Kí á ma wulẹ̀ tún ṣe àwáwí kan lórí ìdá kẹfà mọ́ nítorí pé àwítúnwí ìdá èkíní dé ẹ̀kẹrin ní í ṣe. Ṣùgbọ́n àwọn ìlà 82 dé 87 jẹ́ ìlà ẹlẹ́rìí ẹsẹ Ifá tó bẹ́ẹ̀ tí a kò lè fẹnu fò wọ́n ru. Nínú ìdá keje ni ẹsẹ Ifá yìí ti gún. Àwítúnwí alákùdé tí a fi ọ̀kan-kò-jọ̀kan ẹyọ ọ̀rọ̀ parí ìlà wọn ló jọba níbẹ̀. Ìlà ìkẹ́hìn ló gùn jù lọ níbí nítorí pé àfikún fáàbù ní ẹyọ ọ̀rọ̀ méjì (orúkọ àti ẹ̀yán) níbi tí àwọn ìlà tó ṣíwájú rẹ̀ kò tilẹ̀ ní àfikún rárá. Gígùn ìlà ìkẹhìn yìí kò ṣàìní ìtúmọ̀ gẹ́gẹ́ bí a ó ti rí i bí a bá tẹ̀ síwájú. Ní àkótán, ní òpópó gírámà, ẹsẹ Ifá yìí dà bí ibú onírúnrú sítírọ́kíṣọ̀: Bí a ti ń rí oríṣiíríṣií àwítúnwí, bẹ́ẹ̀ náà ni a bá sẹ́gímà, onírúnrú àṣẹ́ku gbólóhùn, gbólóhùn tó fi ara jọ àlọ́, ìbáà jẹ́ àpamọ̀ tàbí ọ̀kanṣoṣo-bí-orógbó ni o, kò sí orúkọ tí a lè fi pè é tí kò ní bá a mu.

## Ìjìnlẹ̀ Ìtúmọ̀ (Sẹ̀mańtíìkì)

Àpárá kó ìpín pàtàkì nínú àwọn ìjìnlẹ̀ èdè tí ẹsẹ Ifá yìí ń fọ̀. Kódà ohùn àpárá náà ni babaláwo wa fi ṣíde. Ó sì fi bẹ́ẹ̀ fi ẹ̀sìn mùsùlùmí ṣe ẹ̀sín láti ìbẹ̀rẹ̀ dé òpin ẹsẹ Ifá yìí. Nígbà míràn, èdè àpárá yìí a hàn kedere sí ni; ṣùgbọ́n ṣe ni a ó họ ara ẹsẹ ọ̀hún tí a ó tilẹ̀ fẹ́rẹ̀ẹ́ jẹ́wọ́ ọ̀bún kí a tóó lè mọ̀ àpárá tí ń bẹ níbòmíràn tí a kò tilẹ̀ pète rárá.

Ọ̀nà pàtàkì kan tí a lé gbà bí a bá fẹ́ẹ́ fi nǹkan tàbí ẹnìkan ṣe ẹ̀sín ni pé kí a mú ọ̀rọ̀-dún-bí-mo-ti-dún lò bí a bá fẹ́ẹ́ sọ̀rọ̀ nípa ẹnìkan tàbí nǹkan náà. Ṣé agbára káká náà ni a lè fi ka ọ̀rọ̀-dún-bí-mo-tí-dún kún ara èdè. Nítorí ní agbedeméjì èdè àwọn ọmọdé tàbí ohùn àwọn ẹranko àti èdè gidi ni àyè ọ̀rọ̀-dún-bí-mo-ti-dùn wà. Lílò tí a lò ó níbí (wútùwútù) fi hàn ni pé èdè bí ẹnà tàbí èdè àjèjì ṣá ni àwọn tí ń sọ ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ń fọ̀. Kì í ṣe èdè gidi. Kí á rántí òwe Yorùbá tí ó lọ báyìí: *"Bí n kò gbọ́ ègùn, mo ṣáà gbọ́ wọ̀yọ̀wọ̀yọ̀"*. Wọ̀yọ̀wọ̀yọ̀ àti wútùwútù, ọmọ ìyá ni wọ́n láìsí àníàní. Ǹjẹ́ gẹ́gẹ́ bí Ègùn ṣe lọ́ lẹ́nu àwọn Yorùbá, tí ó sì ṣe àjèjì sí èdè wọn, bẹ́ẹ̀ náà ni babaláwo fi n dá a lápàárá pé èdè tó n jáde láti ẹnu àwọn mùsùlùmí kò yé ayé. A rí irú lílo ọ̀rọ̀-dún-bímo-ti-dún bẹ́ẹ̀ nínú ẹsẹ Ifá mìíràn tó lọ báyìí lórí èdè àwọn Tápà:

A díá fún Fátúsì
L'Éǹpe, nílé aléte w'Ọya

Afèdì ọ̀kọ̀ tẹlẹ̀ *fọ mọ̀gàmọ̀gà.*[11]

Ìjìnlẹ̀ àpárá náà ni a ó tùún rí nípa àwọn orúkọ mùsùlùmí tó jáde níbí. Ṣé wọ́n ní orúkọ a máa ro ni. A yan orúkọ mẹ́ta wọ̀nyí ni, kì í ṣe pé a kàn dédé lò wọ́n láìsí ìtumọ̀. Wọn kì í ṣe orúkọ tó wọ́pọ̀ láàrín àwọn mùsùlùmí. A ó kìíyè sí wí pé sílébù ìkẹhìn àwọn orúkọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí jẹ́ fáàbù ní èdè Yorùbá, *bí, tú, dù.* Bí a ba sì darí gbogbo wọn jọ, tí a sì tún fi ìtumọ̀ oníkálùkù wọn wé ara wọn wò láìgbàgbé ẹ̀mí tó gun babaláwo wa kí ó tóó ki Ifá yìí (ẹ̀mí Òtúrá Méjì), a ó ri i pé àwọn fáàbù mẹ́tẹ̀ẹ̀ta lè fún wa ní kọ́kọ́rọ́ fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìtumọ̀ nípa ẹ̀gàn, odì àti ìjà tí ń bẹ láàrín ẹ̀sìn ti láéláé àti èyí titun. Ẹ sá jẹ̀ẹ́ kí á gbìyànjú kí a tú wọn wò:

| | |
|---|---|
| **Gáńḿbí:** | Ọmọ (ẹ̀sìn) tuntun tí a ti *bí* lẹ́hìn ìgbà tí a ti *gán* ti láéláé lórí. Tàbí èyìí tuntun rọ́pò (bí) èyìí láéláé tó ti ń kú lọ. |
| **Kàlìtú:** | A lè ka orúkọ yìí sí ẹ̀dà gbólóhùn *"Kò ní lè tú"* Èyìí ni pé bí ìrókò (ẹ̀sìn tuntun) ṣe ń sọ pé kó wó kó wó, bẹ́ẹ̀ náà ni àràbà (ẹ̀sìn láéláé) ń ṣagbára láti fi ẹsẹ̀ dúró ṣinṣin. |
| **Dáúdù:** | Ẹ̀sìn tuntun ń du ipò ẹ̀sàn àdáyébá. |

Ẹ̀mí ìfinìṣẹ̀lẹ́yà náà ló tún hàn nínú títò tí babaláwo to àwọn orúkọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta, àní bi àwọn ọmọ Ọ̀rúnmìlà ṣe tẹ̀lé ara wọn. Dáúdù ni a fi ṣe àbíkẹ́hìn àwọn ọmọ Ọ̀rúnmìlà. Bẹ́ẹ̀ ni a sì mọ̀ pé nínú àṣà Yorùbá, àkọ́bí ọmọ ní í jẹ́ Dáúdù. Ǹjẹ́ nípa kí a mọ̀ọ́mọ̀ lo ìtumọ̀ orúkọ ní òdì ni a ti lè rí ẹ̀mí ìfinìṣẹ̀ṣín. Bóyá nípa àtòòdì tí akéwì wa to àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí, ó fẹ́ẹ̀ sọ fún wa pé ṣe ni ẹ̀sìn tuntun ń gbìyànjú láti da ẹ̀sìn àtijọ́ rú kí ó sì wá tún gbogbo nǹkan tò. Akéwì kò fi ẹ̀gàn mọ níbi orúkọ nìkan. Nínú ìdá 4, gbogbo ohun tí àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ń ṣe ló dá ẹ̀rín pa ni: Wọ́n wé gèlè (Kò tọ̀nà kí ọkùnrin Yorùbá wé gèlè). Láti ìlà 40 dé 46, ohun tí àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ń ṣe kò nídìí, kò sì ní ìtúmọ̀; wọ́n dà bíi wèrè ("Baba wọn ṣá ń wò ni). Bẹ́ẹ̀ ni wèrè kò sì ṣeé bí lọ́mọ. Ṣùgbọ́n wọ́n ni *"ẹ̀gàn kò póyin má dùn"*. Babaláwo tó ki Ifá yìí mọ̀ pé kò tọ́ kí òun fi ẹnu ẹ̀gàn lásán tẹ́ ẹ̀sìn ìmàle. Nítorí èyí láti ìjìnlẹ̀ ọgbọ́n àti òye ni yóò wáá fi han ni pé òtítọ́ gidi ń bẹ nínú ọ̀rọ̀ àwàdà tí òun ti ń báa bọ̀. Ìlà tó kira jùlọ lọ́nà ibẹ̀ un ni ìlà 8: *"A máa fi gbogbo ara kéwú eléwú kiri"*. Ìfọ̀rọ̀dárà tí babaláwo lò nínú ìlà yí gbayì. Ó ṣe bẹ́ẹ̀ fi òkò kan ṣoṣo pa ẹyẹ méjì. Ìtúmọ̀ ẹyọ ọ̀rọ̀ *kẹ̀ẹ̀wá* yà sí méjì: A lè fi ọgbọ́n ògeere èdè tú u sí àkànpọ̀ ọ̀rọ̀ méjì: a ó rìí fáàbù kan àti orúkọ àfikún: kó + ewú. Bí a bá sì rò ó sí mọ́fímù kan ṣoṣo a ó rìí kéwú-ìwé arábìíkì tí a fi a.b.d. lárúbáàwá kọ.

Wọ́n fi bẹ́ẹ̀ so àmì ogbó (ewú irun-funfun)…àmì nǹkan àtijọ́ tó ti rà, tí kò dára tí kò sì wúlò?...mọ̀ ohun pàtàkì tí a lè fi dá ẹsìn ìmàle mọ̀ (kéwú, ìwé

11 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá, Apá 3*, o.i. 41.

mímọ̀ àwọn mùsùlùmí). Pátápirá rẹ̀ ni pé a fẹ́ẹ̀ mú ni gbàgbọ́ pé ẹ̀sìn ìmàle ti dìkàsì. Ṣùgbọ́n etí nìkan kọ́ ni bababláwo fi ọ̀ràn lọ̀. Ojú náà ní ìpín tirẹ̀ níbẹ̀; èyí sì hàn nínú ìlà 8. Ṣe funfun ni ewú gẹ́gẹ́ bí ẹ̀wù tí àwọn ìmọ̀le máa ń dà bora. Ṣùgbọ́n ní èrò babaláwo funfun ti ìmọ̀le kì í ṣe funfun lẹ́lẹ́ tí ń ya nǹkan sí mímọ́ bí kò ṣe àmì nǹkan abàmì. Ó mú ni rántí ẹsẹ Ifá kan tó lọ báyìí:

Gbogbo orí àfín *ewú*
Abuké ló rẹrù *Òòṣà mọ́ sọ̀…*[12]

Lẹ́hìn náà, *"ewú eléwú"* fi han ni pé ẹ̀sìn ìmọ̀le kì í ṣe tiwa; ẹ̀sìn tí ó tilẹ̀ le mú kí àwọn àjèjì tàbí àbùlẹ̀dó le gàba lórí wa lọ́jọ́ iwájú ni. Ní àkótán ìlà 8 dà bí àlúpàyídà: Ẹ̀sìn mùsùlùmí tí ń ka ara rẹ̀ sí mímọ́ (funfun) àti tuntun (kéwú, ìwé kíkà àti kíkọ, ọ̀làjú) ni akéwì wáá sọ di àmì ohun àtijọ́ (ewú) àti àmì ìgbèkùn (ewú eléwú). Ìlà 8 tilẹ̀ jẹ́ ìlà 5 ní hain ni. Ìjìnlẹ̀ ìfọ̀rọ̀dárà ni a bá níbí gẹ́gẹ́ bí a ti bá a lọ́hùún. Lékèélékèé gbà ju àlàyé kan lọ. Bí a bá fi ojú odindi ọ̀rọ̀ wò ó, ìtúmọ̀ rẹ̀ ni ẹyẹ funfun. Ṣùgbọ́n gírámà èdè Yorùbá fún ni láyè láti le kà á sí àkànpọ̀ ọ̀rọ̀ méjì bákan náà láìluko. Bí a bá sì ṣe báun, a ó rii pé àwítúnwí *ní* + *èkéé ní* í ṣe: Lékèélékèé = ẹni tó ń sábàá máa ṣèkèé, èèyàn tí ń purọ́ tà.

Ẹyọ ọ̀rọ̀ *"ẹyẹ"*, tí a fi so lékèélèkèé pọ̀ mọ́ ìmọ̀le jẹ́ àmì pàtàkì kan. Ṣé a ti mọ̀ tẹ́lẹ̀ pé ẹyẹ ni àmì àwọn ìyàmi òṣòròǹgà, tó bẹ́ẹ̀ tí wọn fi ń pè wọ́n ní ẹlẹyẹ. Yàtọ̀ fún èyìí, ẹyẹ nínú ìlà yí (ìlà 5) dúró fún àmì ìdàgbàsókè (fífò lẹyẹ máa ń fò) gẹ́gẹ́ bí àwọn fáàbù *súúré* (ìlà 3) àti sí (ìlà 6) ti lè jẹ́rìí rẹ̀ àti orúkọ orí. Òpópónà kan náà ni àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ wọ̀nyí mú tọ̀. Ǹjẹ́ ìtúmọ̀ *"lékèélékèé ẹyẹ ìmọ̀le"* ni pé èkéé tàbí irọ́ mà ń gòkè fíofío sí i lójojúmọ́. Ẹsẹ Ifá mìíràn nínú odù Òtúá kan náà jẹ́rìí ìlà yí. Ó ní:

Ìmọ̀le,
Lọ́jọ́ wo lẹ ha gbọ́kú Ọlọ́run Ọba?
*Èkée yín o*
Tí ẹ fi ń gbààwẹ̀….[13]

Bí èkéé (ẹ̀sìn ìmọ̀le) tí ń gòkè bẹ́ẹ̀ náà ló ń tàn ká gbogbo igun mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ayé. Èyí ló tilẹ̀ mú kí ominú máa kọ babaláwo. Ìtakété àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ *sí* àti *bá* pẹ̀lú *ọ̀pọ̀tọ́* àti *òroǹbó* fún ni ní ìwọ̀n ìtànkálẹ̀ èkéé lọ́tùń lósì. Lóòótọ́, *sí* àti *bá* lòdì *sí* ara wọn tí a bá fi ojú fọnọ́lọ́jì àti ti sẹ̀máńtíkì wò wọ́n:

| | |
|---|---|
| ***Sí:*** | àfúnnupè àìlóhùn + Fáwẹ̀lì iwaájú àpẹnumọ́pè + ohùn òkè. |
| ***Bà:*** | àsẹ́nupè olóhùn + Fáwẹ̀lì ẹ̀hìn àyanupè + ohùn ìsàlẹ̀. |

12 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá, Apá 1*, o.i. 21.
13 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá, Apá 4*, Òtúá Méjì, ẹsẹ 5, o.i. 87.

Bẹ́ẹ̀ náà ni ọ̀pọ̀tọ́ àti òrom̀bó. Lọ́nà sẹ̀máńtíkì: Igi oko/igi ilé. Lọ́nà fọnọ́lọ́-jì, ọ̀pọ̀tọ́ ní fáwẹ̀lì àṣíìṣítán mẹ́ta (o), kọ́ńsónáńtì àsẹ́nupè àìlóhùn méjì (p, t). òrom̀bó ní tirẹ̀ ní fáwẹ̀lì àṣéèṣétán mẹ́ta (o), kọ́ńsónáńtì olóhùn méjì (r, b) àti kọ́ńsónáńtì àránmúpè kan (m). àti ọ̀pọ̀tọ́, àti òrom̀bò, igi eléso ni wọ́n. A lè ti ibẹ̀ rò pé igi ẹ̀sìn tuntun ń so, èyí ni pé kò ṣàìní èèyàn lẹ́hìn. Ẹsẹ Ifá mìíràn láti inú Òtúá jẹ́ ni ní han:

Bàbá Mọ̀lé ní òun ni òtútú-ǹtú:
A tú ìbejì sínú ilé ńlá
A tú ìbejì sínú oko gbẹnsẹlẹ
Bí wọ́n ti m̀bí nílé
Ni wọ́n m̀bí lóko…[14]

Ṣùgbọ́n bí a bá rántí pé òrom̀bó ní ẹ̀gún àti pé èso rẹ̀ kan, a tún lè rò pé babaláwo fẹ́ẹ́ fi ye wa pé lóòótọ́ ni ẹ̀sìn ìmọ̀le ń tàn kálẹ̀ ayé, ṣùgbọ́n ìtàn-kálẹ̀ rẹ̀ kò fi bẹ́ẹ̀ rọrùn ní ilẹ̀ Yorùbá.

Bóyá títẹ́wọ́gbà tí gbogbo ayé ń tẹ́wọ́ gba ẹ̀sìn mùsùlùmí yìí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òfo àti ọgbọ́n tí kò múná dóko ni Ifá rí nínú rẹ̀, ló mú kí babaláwo fi ara dà á tí kò dìgbò lù ú mọ́:

"O wáá rántí Ifá
Tí àwọn awoo rẹ̀ẹ́ kì fún un
*Kò bá wọn jà….*

Dípò bẹ́ẹ̀, tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ pàápàá, akápò fi agídí gbìyànjú láti fi han pé Ifá ni baba ẹ̀sìn ìmọ̀le, àti pé láti inú Ifá ni ẹ̀sìn mùsùlùmí ti súyọ. Èyí kì bá tí ṣeé ṣe bí kò ṣe pé sítírọ́kíṣọ̀ ẹsẹ Ifá ló fún un ní àǹfààní bẹ́ẹ̀. Ṣé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹsẹ Ifá ló jẹ mọ́ ọ̀ràndùn nípa àìríbí àìrípọ̀n:

A díá fún Ọ̀rúnmìlà
Ifá ń sunkún òun ò rọ́mọ bí (Ìlà 9 àti 10)

Bí a bá fẹ́ẹ́ ro èdè tí Ifá fọ̀ yìí sí èdè ọ̀gbẹ̀rì, a lè ka àwọn ìlà méjì wọ̀nyí sí míìtì (myth) tí a ó fún ní ìtúmọ̀ lọ báyìí: Ọ̀rúnmìlà (tó dúró fún gbogbo ọmọ Oòduà: mẹ̀tọ́nímì ìran Yorùbá ni a ka Ifá sí níhìn) ń fi ojú méjéèjì wá àtúnṣe, ó fẹ́ẹ́ pìwà dà, para dà: èyí ni pé àwọn baba wa gbà wí pé ẹ̀sìn àwọn nílò àfi-kún. A kì ṣáà gbọ́n tán láyé ni wọ́n ń wí; bẹ́ẹ̀ ni ọmọdé gbọ́n àgbà gbọ́n ni a fi dá Òtù Ifẹ̀. Ǹjẹ́ Ọ̀rúnmìlà fẹ́ẹ́ bímọ kí ọgbọ́n lè báà máa gorí ọgbọ́n nílée rẹ̀

14 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá, Apá 3*, Òtúá Méjì, ẹsẹ 2, o.i. 92.

(àní ní ilẹ̀ Yorùbá). Ibi tó ti ń janpata àti-tún-ẹni-bí yìí (Wọ́n ní ó rúbọ… ó sì rú u) ni ẹ̀sìn ìmàle ti jẹ jáde kúrò láti inú ẹ̀sìn àdáyébá (Ó bí Gánḿbí…abl.). Ifá wáá sọ ara rẹ̀ di ìbẹ̀rẹ̀ àti òpin. Ògúndá Méjì kò ha ti kọ́ wa pé:

Ifá ló lòní
Ifá ló lọ̀la,
Ifá ló lọ̀túnla pẹ̀lú rẹ̀;
Ọ̀rúnmìlá ló nijọ́ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin Òòṣà dááyé?[15]

Gbogbo rẹ̀ wáá já sí òkìrìbìtì gẹ́gẹ́ bí míìtì òṣùmàrè. Ṣé ejò afirùbọnu ni àmì òṣùmàrè: àti orí ìrù ejò, kò sí èyí tí kò ṣe pàtàkì níbẹ̀. Yálà ẹnu ń pọ ìrù ni o, tàbí ó ń gbé e mì ni o, kò sí èyí tí a yàn níbẹ̀ tí kò mú ọgbọ́n dání. Bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ́ ni ìbáṣe láàrin Ifá àti ẹ̀sìn ìmàle. Ìdí nìyí tí a fi ń gbọ́ pé.

Ó wáá rántí Ifá
Tí àwọn awoo rẹ̀ẹ́ kì fún un,
Kò bá wọn jà.

Bí a bá fi ọwọ́ ọ̀tún na ọmọ ẹni, tòsì kọ́ la fi ń fàá mọ́ra bí? A fi àwọn àyọlò láti inú òwe wọ̀nyí dábàá irú àbáṣepọ̀ tó ń bẹ láàrin Ifá àti ìmàle:

1. Ayé la bá'Fá,
   Ayé la bá'Mọ̀le,
   Ọ̀sán gangan nìgbàgbọ́ wọlé.
2. Ifá ó sunlé,
   Ààfáà ó sùnta,
   Ìgbàgbó kò rí ibi sùn mọ́, ó suntẹ́.

Bí a bá yọ àwọn ìgbàgbọ́ kúrò lọ́wọ̀ọ́, ìtúmọ̀ àwọn òwe méjèèjì wọ̀nyí bá ohun tí a ti ń sọ wá mu: èyí ni pé lórí àkàsọ̀ tí a to àwọn ẹ̀sìn tí Yorùbá mọ̀ sí, òkè téńté ni Ifá wà. Ìmọ̀le ń pọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀ lẹ́hìn Ifá ni, ó sì sún mọ́ ọ pẹ́kípẹ́kí. Ṣùgbọ́n bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé hanḥa báyìí ni ọ̀pọ̀lọ fi ju aláàmù lọ, síbẹ̀ ìyàtọ̀ ń bẹ láàrin wọn mànà. Ọ̀rọ̀ kò kún ní ibi pé kí á ní àwọn ẹ̀sìn méjì bá ara wọn tan tàbí pé wọ́n tilẹ̀ dà bí baba (Ifá) àti ọmọ (mùsùlùmí). A kò gbọdọ̀ gbàgbé pé ara èkíní kò fi bẹ́ẹ̀ yọ̀ sí ara èkejì. Bí ọmọ ìta tàbí ọmọ àlè ni Gánḿbí, Kàlìtú àti Dáúdù rí lójú Ọ̀rúnmílà. Wọn kò ṣe déédé, bẹ́ẹ̀ ni wọn kò sì hùwà tó tọ̀nà lójú baba wọn. Míìtì àìgbọràn (Ìlà 35 dé 46) wá kún míìtì òṣùmàrè. A ti rí iru míìtì àìgbọràn bẹ́ẹ̀ nínú Odú Ìwòrì Méjì, ní ibi tí ọ̀kan nínú àwọn ọmọ Ọ̀rúnmílà tí à ń

15 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá, Apá 1*, Ògúndá Méjì, ẹṣẹ 2, 0.i. 101.

pé ní ìgbà-tí-mo-bímọ-tán-ni-wọ́n-ńfọ̀wọ̀-ọmọ̀-mi-wọ̀-mi, kọ̀ láti tẹrí ba fún baba rẹ̀. Nínú Òtúa Méji níbí, gẹ́gẹ́ bí ti Ìwòrì Méjì lọ́hún, irú ọ̀ràn kan náà ló jẹ jáde níbi àìgbọràn yí: Pátápirá rẹ̀ ni ìdàrú àti èérí. Nínú Ìwòrì Méjì, Ifá relé Olókun kò dé mọ, gbogbo nǹkan wáá dà rú nílé aye.[16] Nínú Òtúa Méjì ìdàrú àti ìwà àìmọ̀ náà ló gbẹ̀hìn ọ̀ràn.

Lóòótọ́, láti inú Ifá ni ẹ̀sìn ìmọ̀le ti súyọ. Ṣùgbọ́n nígbà tí yóò ti ibẹ̀ jáde ńkọ́, ṣe ni a ṣi Ifá mọ̀. Àṣírí àti awo tí Ifá fi lé àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta lọ́wọ́ (Ó kọ́ wọn ní dídá awo abl.) ha ńkọ́? Àbájáde rẹ̀ yàtọ̀ gidigidi sí ti ojúlówó lọ́nà tí kò sunwọ̀n. Nítorí pé àṣẹ̀hìnwá àṣẹ̀hìnbọ̀ ìṣúyọ ẹ̀sìn mùsùlùmí láti inú Ifá ni pé: ẹ̀sìn tí a kà sí ìmọ̀ àti ìrànlọ́wọ́ ọmọ aráyé láyé àtijọ́ wáá di ọgbọ́n àṣejẹun àti àkàsọ fún ìmọ̀tara-ẹninìkan:

Bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọmọ náà ṣe
Tí wọn fi ń dárà gbogbo

Kódà ìwà wọ̀bìà tí a ń wí yìí tún hàn ju èyí lọ nínú ẹsẹ Odù Òtúá mìíràn. Ẹ gbọ́:

Jingiri níí fi gbogbo araá jókòó,
A dáá fún Baba Mọ̀le, abẹ̀wù gẹ̀rẹ̀jẹ̀,
*Tí yóò fi ayé gbogbo ṣọ̀fẹ́ jẹ*
*Wọ́n ní ó káalẹ̀,*
Ẹbọ ni kí ó ṣe.
Ìgbà tó rúbọ tán,
Tí ayé yẹ é tán
*Ó ní* ọ̀fẹ́ ni n ó maa jẹ[17]

Lẹ́hìn náà ẹ̀wẹ̀, kò tún sí ọ̀wọ̀ lára ẹ̀sìn mọ́ ní ìwọ̀n ìgbà tí kò sí àṣírí àti awo mọ́. Nǹkan awo ti wáá di nǹkan gbangba dẹkùn kedere bẹ̀ ẹ́ wo, nǹkan ìnáwó, nǹkan ọjà, ní ọ̀rọ̀ kan, ohun tí a le rà. Awo ti kúrò ní ìgbàlẹ̀:

Àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí ó lọ síbẹ̀…
Wọn á ránńṣẹ́ pè wọ́n.

Láìfepo bọyọ̀, àbájáde ẹ̀sìn mùsùlùmí láti inú Ifá ti sọ òye, aájò, ìmọ̀ àti ọgbọ́n fún ìlọsíwájú ènìyàn tí à ń pè ní ìwúlò tàbí iṣẹ́ ẹ̀sìn di iṣẹ́ lásán, láìsí ẹ̀sìn:

16 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá, Apá 1*, Ìwòrì Méjì, ẹsẹ 1, o.i. 43-47.
17 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá, Apá 3*, Òtúá Méjì, o.i. 93.

Wọ́n wá mú un bí iṣẹ́ (ìlà 54).

Èyí wáá dà bí ìgbà tí páńsá tí a fi há sí òkè já lulẹ̀, tàbí kí ìràwọ̀ já láti ojú sánmà. Bóyá jíjá tí ohun tí a gbé ga jù lọ (Ifá) já ló jẹ́ kí babaláwo lè ronú ilé ayé, tí ó sì kọ ẹ̀hìn sí ọ̀run láìsí ìrọ́kẹ̀kẹ̀, ni àbáyọrí ẹsẹ Ifá rẹ̀. Àbáyọrí ẹsẹ Ifá yìí tilẹ̀ sunwọ̀n púpọ̀. Ó sì tún kọ́ ni lọ́gbọ́n pé kò sí ohun tó ju ènìyàn lọ lábẹ́ ayé. Ó fẹ́rẹ̀ẹ́ dà bí ẹni pé ohùun *"wí"* (lẹ́tà w) ni babaláwo fi ń lùlù níbí. A sì gbọ́ ìró W yìí gẹ́gẹ́bí gboùngboùn ìlù kan tí a ti gbọ́ rí ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Òtúa yìí. Ẹ̀ẹ̀mẹsàán ni a lo ohùn W nínú ìlà mẹ́rin ìdá keje tí í ṣe àbáyọrí ẹsẹ Ifáa wa yìí, (Ìlà 88-91). Báyìí ni wọ́n sì pín ara wọn sí nínú ìlà mẹ́rẹ̀ẹ̀rin wọ̀nnì:

| | |
|---|---|
| Ìlà àkọ́kọ́: | 2W |
| Ìlà kèjì: | 3W |
| Ìlà ẹ̀kẹta: | 2 W |
| Ìlà ẹ̀kẹrin | 2 W. |

Láàrín àwọn fáwẹ̀lì tó tẹ̀lé ohùn W ní ìparí ẹsẹ yìí, àwọn fáwẹ̀lì àyanupè ló wọ́pọ̀. Èyí lòdì sí ohun tó ṣẹlẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá yìí níbi tí a rí kìkìdá U tí í ṣe àkọ́kọ́ nínú àwọn fáwẹ̀lì àpẹnumọ́pè. Kín ni ìtúmọ̀ tí a ha lè dábàá fún ìyàtọ̀ láàrin lílò fáwẹ̀lì ní ìbẹ̀rẹ̀ àti ní ìkádìí ẹsẹ Ifá yìí. Ó lè jẹ́ pé ìyàtọ̀ yìí ń tọ́ka sí ìrètí àti ìṣípayá sí ọ̀ràn ayé àti ìlọsíwájú ènìyàn, yàtọ̀ fún ohun ìṣáátá tí a gbọ́ ní ìbẹ̀rẹ̀. Bóyá irú ètò ojú-òdì tí ń bẹ nínú sẹ̀máńtíìkì àwọn ìdá 1 àti 7 ló tún hàn jáde nínú fonọ́lọ́jì tí í ṣe aṣọ ìbora rẹ̀: U nìkan nínú ìdá àkọ́kọ́ kí á fi ta kò ***o*** méjì, ***ọ*** kan àti ***a*** mẹ́fà nínú ìdá keje. Ìtúmọ̀ ètò ojú-òdì yí ni pé ní ìbẹ̀rẹ̀ ẹsẹ Ifá (ìdá 1) èdè mùsùlùmí (wútùwútù) kò yé akápò; ó dà bí ẹnà tàbí èdè awo tí kò le hàn sí ọ̀gbẹ̀rì tàbí ẹnikẹ́ni. Èyí ló fa lílo ògédé U, fáwẹ̀lì àpẹnumọ́pè. Ṣùgbọ́n nínú ìparí ẹsẹ wàyí o, ìdá keje ti tan ìmọ́lẹ̀ sí awo, àṣírí àti ìtúmọ̀ ẹ̀sìn mùsùlùmí àti pàápàá ẹ̀sìnkẹ́sìn. Ìdí nìyí tí fáwẹ̀lì tó yè koro (àyanupè) ṣe wọ́pọ̀.

Ẹyọ ọ̀rọ̀ àwa, tí a rí nínú ìlà mẹ́rẹ̀ẹ̀rin àti lẹ́ẹ̀mẹta ní ìbẹ̀rẹ̀ ìlà ṣe pàtàkì ní ìkádìí ẹsẹ yìí. Ó sì ń bèèrè fún ìtúmọ̀. *Àwa* níbí já sí *'àwa tìkárawa'*, (èyí ni pé àwọn onífá) pẹ̀lú ẹ̀yin ìmọ̀le àti àwọn ẹ̀sìn míràn tí a mọ̀ tàbí tí yóò wáyé níjọ́ iwájú. Èé ha ti ṣe tí babaláwo wá ń so àwọn ẹ̀sìn wọ̀nyí pọ̀ nígbà tí ó ti fi wọ́n ta ko ara wọn ní ìbẹ̀rẹ̀? A rò pé bóyá ẹ̀mí ìfẹ́ tàbí ti ìfaradà, tàbí méjèèjì pọ̀ ló gùn ún. Ìfaradà nítorí ẹ̀sìn tuntun ṣá ń fẹsẹ̀ rinlẹ̀ bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé kò wú onílàákàyè lórí tó ẹ̀sìn àdáyébá tó bẹ́ẹ̀ tí kò tọ́ kí á kó o máyà (ká fẹ̀wù àlàárì fọnkun àmódi). Ẹ̀mí ìfẹ́ àti ìtẹ́wọ́gbà ní ìwọ̀n ìgbà tí babaláwo ní ìkadìí ọ̀rọ̀ rẹ̀ ti wáá já ọgbọ́n èké tó so gbogbo àwọn ẹ̀sìn pọ̀: òun ni ìfẹ́ sí nǹkan ìṣúra ayé yìí (owó, ọmọ, àtubọ̀tán ayé). A fi bẹ́ẹ̀ yé ni pé òpè ènìyàn ló lè tìtorí ẹ̀sìn bá ọmọ ẹ̀nìkejì rẹ̀ ja àjàkú, nítorí *"ẹnu là ń bọ"*. Ifá náà ló sọ báyìí pé:

Àteégún, àtòòṣà,
Lóòótọ́ lajé jù wọ́n lọ,
Ajé jù wọ́n lọ lóòótọ́.[18]

Àwọn ìlà 89 dé 91 tẹ́ ẹní fáwẹ̀lì mẹ́ta: *o, ọ* àti *a*. Ẹ̀ẹ̀mẹta ni a sì lo ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn láti àfikún fáàbù wá lọ. A ó sì ṣe àkíyèsí pé a kò ṣàdéédé lo àwọn orúkọ mẹ́ta tíí ṣe àfikún fáàbù *wá,* tí wọn sì jẹ́ kókó ọ̀rọ̀ inú ìkadìí ẹsẹ yìí. A tò wọ́n sórí àkàsọ̀ láti ilẹ̀ dé òkè bí wọ́n ṣe ń tẹ̀ lé ara wọn mà ni. Pẹ̀lúpẹ̀lú bí a bá fi ojú fonọ́lọ́jì wò ó, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni àwọn fáwẹlì ń ṣí sí i bí a ṣe ń gòkè sí i lórí àkàsọ̀ yẹn. *O* ni àtètèkàn, *ọ* ní a fi tẹ̀ ẹ́, *a* lé té lórí gbogbo wọn:

*o... ọ... a*
owó
ọmọ
àtubọ̀tán ayé

Ó tilẹ̀ jọ ni lójú pé a rí palíńdóòmù (palindrome) méjì tó sunwọ̀n jọjọ láàrín ìlà mẹ́rin wọ̀nyí. Lẹ́ẹ̀kan sí i, ṣe ni àwọn palíńdóòmù náà tún tẹ̀ lé ara wọn lórí àkàsọ̀; nítorí pé *"owó"* kì í ṣe palíńdóòmù kíkún, alákùdé ni: a kò le kà á láti ọwọ́ ọ̀tún gẹ́gẹ́ bí a ti ń kà á láti ọwọ́ òsì nítorí ohun yàtọ̀ lórí àwọn fáwẹ́lì *O* méjéèjì. Ṣùgbọ́n ojúlówó palíńdóòmù ni *"ọmọ"*. A le kà á bákan náà láti ọwọ́ ọ̀tún àti òsì. Ó sì fẹ́rẹ̀ẹ́ jọ pé kíkún tí palíńdóòmù *"ọmọ"* kún fi hàn wá pé ni èrò Yorùbá láye ijọ́un, ọmọ ju owó lọ ni.

Fáàbù *tán* àti orúkọ *ayé* tí babaláwo fi ti ẹsẹ Ifá rẹ̀ yí kò mú ìyanu wá fún ni. Ayé la mọ̀, ọ̀run lojú wa kò tó. Ayé sì ni ìbẹ̀rẹ̀ àti òpin àti òsùnwọn ohun gbogbo. Ohunkóhun tí ó wù kí èèyàn fi pọ́n ara rẹ̀ lójú láti ibi ẹ̀sìn, òtúa (asán, òtúbáńtẹ̀) ni. Ó mú ni rántí òótọ́ ọ̀rọ̀ tí ọ̀jọ̀gbọ́n Faransé kan, ọ̀gbẹ́ni Leprince Ringuet, sọ báyìí: *"Ohun tí ewì ń lépa kò ju pé kí ó gbé ayé mì lọ"*.[19]

A gbà pé àwa Yorùbá òde òní kọ́ ní akápò ní lọ̀kàn nígbà tó ki Ifá yìí, síbẹ̀ ẹ̀kọ́ tí a lè kórè níbẹ̀ kúrò níba. Ìkìlọ̀ pé kí a má maa ti ibi ìyàtọ̀ nípa ìgbàgbọ́ tàbí èrò kórìíra ara wa wúlò púpọ̀ ní ayé òní ju ayé ijọ́un lọ. Ifá náà kọ́ ló ní

18 Abimbọla, *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá, Apá 1,* Ìká Méjì, ẹsẹ 3, p 120.

19 Wọ́n ní: A díá fún Ayélẹ̀gún,
Yóò gbédèe rẹ̀ sọnù,
Gbogbo aye ní ọ̀ mọọ bá a wá a kiri. (Abimbọla, *Àwọn Ọmọ Odù*, Àpólà Ogbè, Ọ̀kànrìnsodè, Ẹsẹ Ẹ̀kẹta, 263).

Irú ìtúmọ̀ tí a fún un lábẹ́ orí ọ̀rọ̀ yìí ṣe dédé pẹ̀lú ohun tí Wande Abimbọla sọ nínú: "Ifá Divination Poetry and the Coming of Islam to Yorùbáland: A Preliminary Investigation nínú *Pan African Journal* Volume IV, No. 4, New York, fall 1971. Ojú ewé 440 dé 452. Bẹ́ẹ̀ sì ni, "Mọ̀rìwò ọ̀pẹ̀ ò wí fún raa wọn tẹ́lẹ̀
Tí wọ́n fi ńyọ".
Ifá náà ló wí báun.

*“ọràn ìsìnyí wọn ò tó'jà”*[17] bí ìmọ̀ràn míràn tí a tún lè mú lò ní ayé òní láti ẹsẹ Ifá yìí ni ọgbọ́n pé kí ohun àlùmọ́ọ́nì wa ní òpópónà àṣà tàbí èdè wa máa jọ wá lójú, kí a sì yé é máa *“garùn wọlá ọlọ́lá”*.[18]

Ẹwà ẹsẹ Ifá yìí kò fi gbogbo ìgbà faṣọ bora. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ ọnà tí babaláwo fi ṣe ẹsẹ ọ̀hún lọ́ṣọ̀ọ́ ló hàn. Síbẹ̀síbẹ̀ túláàsì ni aṣọ ìbora, a gbọ́dọ̀ gbìyànjú kí á ṣàlàyé díẹ̀ nípa ìdí rẹ̀ tí a fi ni ewì kan dára bí ó ti wù kí ó sunwọ̀n lójú wa tó. Ìdí nìyí tí a fi ìrànlọ́wọ́ lìǹgúísítíìkì hú díẹ̀ nínú ẹwà yí jáde láti ibi àjà mẹ́ta tí a gbàgbọ́ pé èdè ní: fonọ́lọ́jì, gírámà àti sẹ̀máńtíìkì. A kò sì fi bẹ́ẹ̀ gbàgbé pé ẹwà kì í ṣe ohun tí a lè là sí wẹ́wẹ́ kí á tẹ́ ẹ sórí àtẹ. Ọ̀kan ṣoṣo bí orógbó ni. Ìwọ̀n ni a sì ní láti polówó ọbẹ̀ tó dùn mọ. Ìdí nìyí tí a fi ń ṣẹ́ oyún ọ̀rọ̀ tí a ní sínú tí a fẹ́ẹ̀ sọ lórí ẹsẹ Ifá yìí nígbà míràn.

Dájúdájú, ó lòdì sí àṣà àti ìṣe, pé kí á fi ọ̀rọ̀ bí ìwàásù tàbí ìsúre kádìí èrò ẹni, bí a bá ń ṣe ìwadìí tàbí iṣẹ́ onímọ̀ bí irú eléyìí lórí lítíréṣọ̀. Bí a bá yapa sí irú àṣà àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n yìí a ń tọrọ gááfáà o. Ṣùgbọ́n kì í ṣe pé a ṣáko lọ ni. Ìdí abájọ sì ń bẹ. A rò pé bí a kò bá ṣe bẹ́ẹ̀, Ifá yóò hun wá. Ẹ̀kọ́ ńlá tí a gbọ́dọ̀ ti ibi kíka àwọn ewì àdáyébá kọ́ ni ìrẹ̀lẹ̀. Nítorí pé nípa kí á fi ọgbọ́n, òye, ìmọ̀ àti ẹwà hun ara wọn pọ̀ nínú èdè kí a sì fi bẹ́ẹ̀ gbé awẹ́lẹ́wà ewì kalẹ̀, àwọn baba wa ni ará iwájú, àwa ni èrò ẹ̀hìn. Ṣùgbọ́n lónìí yìí tí a ti di *“Ayélẹ̀gún”* ńkọ́o?[19] Òwèrè ló kù tí a ń jà. Àwọn akéwì òde òní mìíràn kò tilẹ̀ fi ara balẹ̀ kọ́ ọgbọ́n àdáyébá tí baba wa fi ń to ewì wọn àti iṣẹ́ ọnà tí wọn ń ṣe sí wọn lára kí wọn tóò hán kálámù wọn pé àwọn n kọ ewì. Bẹ́ẹ̀ sì ni ìrẹ̀lẹ̀ ni ìpẹ̀kun ẹ̀kọ́. A kò wí pé kí a máa yọ ètò tuntun jáde nípa ewì kíkọ lóde òní. Ń dáa o. Èrò jọ-mi-jọ-mí jìnà sí ọkàn wa. A sì tilẹ̀ gbàgbọ́ pẹ̀lú pé ìwọ̀n là á jọ baba ẹní mọ. Ṣùgbọ́n ògúlùǹtu náà là á fi í kọ́lé tó lágbára. A kò le dábàá ètò titun nípa ewì kíkọ láìmọ òfin tó de ewì fífọ̀ àwọn baba wa. Nítorí bẹ́ẹ̀ nínú ẹ̀kọ́ nípa Ifá, iwì, ègè, ìjálá, ẹ̀fẹ̀, alámọ̀, rárà, olele…abl., ni ìgbàlà ewìiwa wà o. Kí á kọ́ ẹ̀kọ́ nípa rẹ̀ kò sì tó kí àwa alára máa pè wọ́n. Èyí ṣe pàtàkì púpọ̀ nítorí ogunlọ́gọ̀ *“ọ̀mọ̀wé”* òde òní ló ń rò pé kò sí ọlàjú nípa pé kí akọ̀wé máa sun rárà. Wọ́n ti wáá pín ayé sí ọ̀wọ́ méjì: kíkọ ni talákọ̀wé, pípè ni tagbe. Irú èrò àti ìwà báyìí kò mọ́gbọ́n dání pẹ́ẹ̀pẹ́ẹ̀. Bí a kò bá sì fi ọwọ́ wọn bọlẹ̀, kí á yárá lọ mọ̀ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ewì tí a ń kọ lónìí tí à ń pọ́n tí a sì ń rọ́ kẹ̀kẹ̀ sí wọ̀nyí kò ní ní ẹ̀mí gígùn. Ó mú mi rántí orin àwọn oníjàálá kan tó lọ báyìí:

| | |
|---|---|
| **Ọdẹ**: | Ẹ́ é gberin, à bẹ́ ẹ̀ gberin |
| **Àwọn elégbè rẹ̀:** | Bí ọ bá pọ̀ṣé a ò níí gbè. |

Ọ̀rúnmìlà afẹ̀dèfẹ̀yọ̀, Ẹ̀là Ìsòdè kò níí jẹ́ kí á fi èdè Yorùbá pọ̀ṣé o.[20]

20 Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ 'Sopé Oyèláràń, kòfẹ́sọ̀ Ayọ̀ Bámgbóṣé àti awo 'Wande Abimbọ́lá fún ìmọ̀ràn àti ìrànlọ́wọ́ tí wọ́n fún mi. Gbogbo àléébù àti èérí inú iṣẹ́ yìí, tèmi ni. Mo si fi sosùn, mo fi para. Ìdákúdáà lọmọdéé dá'Fá o. A ó rí i pé a yá àwọn ọ̀rọ̀ mélòó kan láti inú èdè Òyìnbó. Kò sí láburú ní ibi pé kí á máa lo àwọn ọ̀rọ̀ bíi fonọ́lọ́jì tàbí lítíréṣọ̀, tó ti wọ

## Àfikún I

***a. Zeugma:*** Nínú lítíréṣọ̀ àwọn òyìnbó, ìbáà ṣe "Gẹ̀ẹ́sì, Faransé, Pàyáàn tàbí Rọ́síà, ohun tí a ń pè ní zeugma ni àfẹ́kù ẹyọ ọ̀rọ̀ kan (pàápàá jùlọ ọ̀rọ̀ ìṣe tàbí ẹ̀yán ọ̀rọ̀) nínú ìlà méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ níbi tí a ń retí rẹ̀ nítorí pé ó ń bẹ nínú ìlà iwájú tí a sì mọ̀ dájúdájú pé eléyìí bá àwọn ìlà wọ̀nyí dọ́gba.

***b. Palindrome:*** Ẹyọ ọ̀rọ̀ tí a le kà bákan náà yálà láti òsì dé ọ̀tún gẹ́gẹ́ bí a ti ń ka ìwé, tàbí láti ọ̀tún dé òsì, gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti ń ka kéwú ni àwọn Òyìnbó ń pè ní palindrome. Àpẹẹrẹ láti mú èdè Yorùbá.

*Ọ̀wọ̀, òwò, ọlọ.*

## Àfikún II

Òtúá Méjì
Wútùwútù yáákí;
Wútùwútù yám̀bèlé;[21]
Ká súré pátápirá,
Ká fẹ̀wù àlàárì fọnkun àmódi;

Lékèélékèé, ẹyẹ ìmọ̀le,[22]
Bó bá ṣí lórí ọ̀pọ̀tọ́,
A bà sórí òrom̀bó,
A máa fi gbogbo ara kéwú eléwú kiri;
A díá fún Ọ̀rúnmìlà,

---

inú ọ̀pọ̀lọpọ̀ èdè àgbáyé. A sì rò pé ìdí rẹ̀ hàn sí gbogbo wa. Ṣùgbọ́n a gbàgbọ́ pé àwọn ọ̀rọ̀ míràn wà tí a yá lò, tí a sì rò pé bí a bá ronú jinlẹ̀, a lè rí ìtumọ̀ wọn tàbí ọ̀rọ̀ tí yóò dúró fún wọn ní èdè Yorùbá. Àwọn wọ̀nyí ni àwọn ọ̀rọ̀ bíi palíndóòmù, ségímà…abl., tí a fi ẹ̀dà wọn ní èdè Gẹ̀ẹ́sì sí ẹ̀gbẹ́ wọn nínú àdìtú yìí. Àwọn wọ̀nyí ni a lè sọ pé a yá lò lóòótọ́, èyí ni pé a ó dàá wọn padà sínú èdè wọn níjọ́ iwájú bí àwa náà bá wáá rí ọ̀rọ̀ tí a ó fi rọ́pò wọn nínú èdè Yorùbá. Àwọn ọ̀rọ̀ míràn wà tí a kò ṣiyèméjì láti túmọ̀ wọn. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, *open vowel* tàbí *fricative* tí a pè ní fáwẹ̀lì àyanupè àti àfúnnupè. Ṣùgbọ́n ní gbogbo ìgbà àti fún gbogbo ọ̀rọ̀ kọ́ ni èèyàn le dá ara rẹ̀ lójú báun. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀rọ̀ làwa náà lò tí kò sí tíì tẹ́ wa lọ́rùn. Àti pé, pàápàá jùlọ, a gbàgbọ́ pé ọ̀ràn lílo àwọn ọ̀rọ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí irinṣẹ́ láti fi kọ ẹ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ lórí èdè àti lítíréṣọ̀ wa ní èdè Yorùbá kì í ṣe ọ̀ràn ẹnìkan ṣoṣo. Nítorí èyí ni a ṣe ń ké pè yín pé kí ẹ bá ni dá sí i. Ẹ bá ni wo ọ̀ràn yí nítorí ojú kan kìí rọ́ràn ni wọ́n wí. Wàyí o, àìdúrò nijó. Nínú lílo èdè wa fún àròkọ iṣẹ́ onímọ̀ èdè náà ni a ó ti máa kó àwọn ọ̀rọ̀ tí a nílò jọ díẹ̀díẹ̀. A kò lè dúró kí wòlíì kan tàbí ẹnikẹni rọ̀jọ̀ wọn sí wa lọ́kàn láti òkè ọ̀run. Ṣe ló sì yẹ kí á ronú jinlẹ̀ kí á sì jíròrò lórí ìlànà tí a ó tọ̀ kí a tóó bẹ̀rẹ̀ síí ṣẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ tí a nílò. Èdè wa náà ni yóò wáá ṣe asẹ́ tí yóò yan àwọn tó wúlò nínú gbogbo ọ̀rọ̀ tí a ń ṣẹ́. Kí á ṣá màá fọ èèbó gbàgbé àfira náà ni pàtàkì.

21 *Wútùwútù yáákí: wútùwútù yám̀bèlé;* à ń fi eléyìí sín àwọn ìmọ̀le jẹ nípa bí kéwúu wọn ti ń dún létí ẹni tí kò gbọ́ kéwú.

22 *Lékèélékèé, ẹyẹ ìmọ̀le:* àwọn ìmọ̀le fẹ́ràn aṣọ funfun bí aṣọ ara ẹyẹ tí ń jẹ́ lékèélékèé.

Ifá ńsunkún òun ò rọmọ bí.
Wọ́n ní ẹbọ ní ó wáá rú,
Ó sì rú u,
Wọ́n ní ó réku méjì olùwéré;
Kò rẹ́ja méjì abìwẹ̀gbàdà;

Obídìẹ méjì abẹ̀dọ̀ lùkẹ́lùkẹ́;
Ewúrẹ́ méjì abàmú rẹdẹrẹdẹ;
Einlá méjì tó fiwo ṣòṣùká.
Gbogbo rẹ̀ náà ló rú.
Ìgbá tí Ọ̀rúnmìlà ó kọ̀ọ́ bí,

Ó bí Gánḿbí.[23]
Ìgbà tí ó tùún bí,
Ó bí Kàlìtú.[24]
Ìgbà tí ó tùún bí,
Ó bí Dáúdù,[25]

Èyí tíí sọmọ ìkẹ̀yìn wọn léńje léńje.
Ikú kò pa wọ́n,
Àrùn kò ṣe wọ́n.
Ìgbà tí wọ́n dàgbà tán,
Ọ̀rúnmìlà kọ́ wọn ní dídá ọwọ́,

Wọ́n mọ̀ ọ́n dá
Ó kọ́ wọn létìtẹ̀ alẹ̀,
Wọ́n mọ̀ ọ́n tẹ̀.
Ó kọ́ wọn ní ọ̀karara ẹbọ,
Wọ́n mọ̀ ọ́n há.

Nígbà tó dọjọ́ kan,
Ni wọ́n bá ré agbádáa babaa wọn,
Wọ́n ré gèlè ìyáa wọn;
Wọ́n wọ agbádá náà,
Wọ́n sì wé gèlè náà sórí bàǹtùtù,

23 *Gánḿbí:* Orúkọ ọmọ ìmọ̀le.
24 *Kàlìtú:* Orúkọ ọmọ ìmọ̀le.
25 *Dáúdù:* orúkọ ọmọ ìmọ̀le ni èyí náà.

wọ́n na igi mẹ́rin sílẹ̀ níbùú-níbùú.[26]
Wọ́n wáá kó sí ààrin àwọn igi náà,
Wọ́n ń ṣẹnu wújẹ́wújẹ́,
Wọ́n ń foríí kanlẹ̀,
Wọ́n ń dìde.

Wọ́n ń kúnlẹ̀,
Wọ́n sì ń nàró.
Bàbáa wọ́n ṣá ń, wò wọ́n ni.
Wọ́n ń ṣe bẹ́ẹ̀ lẹ́ẹ̀maàrúnmárùún lójoojúmọ́.
Ó wáá rántí Ifá

Tí àwọn awoo rẹ̀ẹ́ kì fún un,
Kò bá wọn jà.
Kẹ̀ẹ̀kẹ̀ẹ̀ kiní yìí ń wọ̀ wọ́n lára.
Ìgbà tó yá,
Wọ́n wáá mú un bí iṣẹ́.

Ó di wí pé
Bí ẹnìkan ba ń sọ ọmọ lórúkọ,
Àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí ó lọ síbẹ̀.
Bí òkú kú fún ẹnìkan,
Wọ́n á ránńṣẹ́ pè wọ́n.

Bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọmọ náà ṣe
Tí wọn fi ń dárà gbogbo.
Ìgbà tí wọn dàgbà tán,
Tí àwọn náà bímọ.
Bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn ọmọ wọn ń ṣe

Ijó ni wọ́n ń jó,
Ayọ̀ ni wọ́n ń yọ̀;
Wọ́n ní bẹ́ẹ̀ gẹ́ẹ̀
Ni awo àwọn ń ṣẹnu rereé pefá.
Wútùwútù yáákí;

Wútùwútù yám̀bèlé;
Ká súre pátápirá;

26 *Wọ́n na igi mẹ́rin sílẹ̀ níbùú-níbùú:* Àwọn Ìmọ̀le a máa na igi sílẹ̀ bàyìí láti fi ṣe mọ́sáláásí.

Ká fẹ̀wù àlàárì fọnkun àmódi;
Lékèélékèé, ẹyẹ ìmọ̀le,
Bó bá ṣí lórí ọ̀pọ̀tọ́,

A bà sórí òrom̀bó,
A máa fi gbogbo ara kéwú eléwú kiri;
A díá fún Ọ̀rúnmìlà,
Ifá ń sunkún òun ò rọ́mọ bí.
Wọ́n ní ó káakí Mọlẹ̀,
O jàre,
Ẹbọ ní ó ṣe.
Ó gbọ́ rírú ẹbọ,
Ó rú.
Ó gbọ́ èrù àtùkèṣù,

Ó tù.
Ó gbọ́ ìkarara,
Ẹbọ́ ha fúnn un.
Ire mẹ́ta làwá ń wá:
Àwá ń wówó o,

àwá ń wọmọ;
Àwá ń wá àtubọ̀tán ayé.